ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV N0 811 LAGOS SATURDAY MARCH 17. — MARCH 23, 1962. KỌBỌ MEJI (2D)

# AGUTAN BIMO MEJI, OKAN ERAN, EKEJI ENIA, NILU OGOJA

Ogoja-- Irohin ti a ri gbọ lati abule Okuni ti o wa nitosi Obubra n i agbegbe i l u Ogoja ipinlẹ Ila-orun ilẹ Nigeria, jẹ agbayanu irohin, wipe ẹran agutan kan bi ọmọ meji, ọkan jẹ ẹran, ekeji j ẹ enia.

Nigbati awọn a r a abule na r i abami ọ m ọ ti ẹran agutan bi yi, ariwo ta ! awọn ara abule keji ati ẹkẹta nrọ giri-giri wa fi onjẹ oju f'oju. Koda, awọn enia fa ilẹkun ile olowo ẹran agutan n a ya nigbati nwọn ndu ọna lati wọle kọja si ẹhinkule lọ wo abami ọmọ enia ti agutan bi.

Onirohin wa sọ wipe ọmọ ti ẹran agutan na bi ni oju gẹgẹbi ti enia, o si ni irun lori, o ni ẹsẹ meji ati ọwọ tinrin-tinrin meji pẹlu ọmọ-ika ọ w ọ bakanna. Ṣugbọn o yọ iru ni idi rẹ, irun si bo ni idaji ara. Agbọ wipe abami ọmọ ẹran na ku lẹhin wakati diẹ ti o d'aiye.

"Ohun iyanu ki i tan l'aiye".

## Ayorunbo Kan Pada Sile Nilu Oyinbo

LONDON—O to nkan bi oṣu meji nisisiyi ti nwọn sọ wipe ọmọbinrin kan, Pauline Magee, ẹni ọdun mẹrindinlọ-gbọn ti nwọn ti kede wipe o ku s'omi odo ti nwọn npe ni Thames, ti nwọn ti ṣe iwadi iku rẹ ni Kotu ti Kotu si ti f'okele wipe "O ku iku riri sinu Odo,' ni arin oṣu January tokọja ninu ọdun yi ni a tun gbọ wipe o pada wa sile laipẹ yi.

Bi ọrọ na ti lọ niyi: nigbati awọn ara ile Pauline fi ṣe awati, nwọn fi ikede sita wipe awọn ko ri enia wọn o, ko pẹ na ni awọn Ọlọpa lọ ri oku obinrin kan ti o fo ninu odo Thames, nwọn si pe awọn enia ti ko ri Pauline lati wa jẹri si bi on ni tabi ki iṣe ẹni ti wọn.?

Ẹlẹri ti o lọ wo sọ wipe bẹni, Pauline Magee ti awọn nwa ni ni. Asamọ-ṣamọ jijọ ni o jọ, on kọ. Nigbati o pada wa sile ni o di ẹrujẹjẹ fun awọn ara ile rẹ, lọgan ni nwọn tun lọ sọ ni Kotu, ti Kotu si yi idajọ ti akọkọ pada wipe aṣiṣe ni. obinrin na kọ l'oku.

## Egbe Omo Eko
## Lagos Citizens' Council

EKO—Awọn ogunna gbomgbo ninu awọn ọmọ ilu Eko, pẹlu awọn saraki enia ni igun mẹrẹrin ilu Eko ti panupọ lati da ẹgbẹ kan silẹ ni ilu Eko ti yio maa ja fun ilọsiwaju ilu Eko, ti yio si ri wipe ko ni si itujẹ tabi ifasẹhin fun awọn ọmọ Eko mọ.



OLOYE BAYỌ DOHERTY
"Ẹni a mbuku t'Ọlọrun mbukun"

Ninu eto ti a ti ṣe nisisiyi fun iṣelu, ilu Eko ti o jẹ aṣiwaju ninu gbogbo ilu ti o wa ni ilẹ Nigeria fẹ r'ẹhin nitoripe ẹnu awa ọmọ ilu Eko ko ṣe ọkan.

Bi awọn apakan ti nsa agbara lati gbe ilu Eko ga si, bẹni awọn apakan nfa s'ẹhin.

Gbogbo eto ati aye giga, ti ilu Eko wa ni o ti fẹrẹ parẹ tan.

1. Ọmọ Eko ko ri iṣẹ ṣe mọ.
2. Ọmọ Eko ko ri iṣọ t a ọja mọ.
3. Ọmọ Eko ko ri ilewe wọ mọ.
4. Ọmọ Eko ko ri o w o (trade) ṣe mọ.
5. Pataki julọ, ọmọ Eko ko ri onjẹ jẹ mọ.

Ilu Eko di gbẹfẹ fun awọn ajoji enia. Ẹgbẹ ọmọ Eko ti ṣe tan lati ri si awọn ohun wọnyi.

Iwọ ha ti fi orukọ silẹ bi? Tara lọ si N0. 25 Ọdunlami St, ki o lọ fi orukọ rẹ silẹ pẹlu awọn ọrẹ rẹ.

NO. 24.

**Federation Of Nigeria**
**THIRD DEVELOPMENT LOAN**

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £7 million registered Stock in February March, 1962. The Stocks to be issued will be:—

1 £2 million 5% Federation of Nigeria Third Development Stock 1966—to be repaid in full on 7th June, 1966.
2. £5 million 6% Federation of Nigeria Third Development Stock 1986—to be repaid in full on 7th June, 1986.

Both Stocks will be issued in multiples of £10 at par, and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the Central Bank during the period 26th February to 26th March 1962.

Prospectuses, which contain full information, and application forms may be obtained from banks or at the Central Bank on or after 26th February, 1962.

W. A. TIBBLES
General Manager
CENTRAL BANK OF NIGERIA,
FEBRUARY, 1962.

# IJOBA IWO ORUN TI GBA OKO TOPO

BADAGRY - Lenu loloyi ni awon Ijo Sosi Aguda l'Eko se ikede wipe Oko ala-gbon ti awon ni ni erekusu Topo n. Badagry ti kuro lowo awon, o si ti di ti Ijoba ipinle Iwo-orun. Fun opolopo odun sehin ni Oko alagbon yi ti je ilu kan pataki fun awon Ijo Sosi Aguda, nibe ni a ti ko ogunlogo awon enia-dudu ti o nse ise Padi l'oni.

Opolopo awon omo ti ko ba di omojaguda ati janduku enia ni a ti ko l'eko nibe ti nwon si di enia rere l'ode oni. Ki Ijoba to da eko ofe sile nibikibe ni ile Nigeria ni awon Ijo Aguda ti nfun awon talaka l'eko ofe ni Topo ti nwon si tun ako nwon bi a ti se nse ise owo l'oko lodo.

O to odun marunlelogorin nisisiyi ti Alfa Padi kan ti oruko re nje Rev. Father Jean-Paul Pouret ko eru re kuro ni ilu Dahomey ti o si lo do si erekusu Topo, eyiti o di oriesun il'owo-wo'le fun Ijo Sosi Aguda nipa tita agbon si awon omo ile'we ibe gbin.

Awon Alase Ijoba ipinle Iwo-Orun si ti se ipinnu wipe awon yio tun oko alagbon erekusu yi se fun anfani awon omo ile eko ti nwon sese jade ni ilewe. Ti o fe fi ise oko se ise asejeun won, awon yio si maa ko awon omodekunrin na ni ise-owo miran pelu.

## Iya Serafu kan Pokunso.

IHIOMA.—Ariwo ekun gbojikan ni aipe yi ni abule Okwuabala ni Ihoama l'agbegbe Orlu ni ipinle Ila-orun nigbati irohin tan kakiri agbegbe ilu na pe iya Serafu kan ti oruko re nje Nwafo Onyeakpoloha pokunso ni irole ojo Satide. Eni odun mokandiladota ni obinrin na, o si je Oloye pataki ninu awon omo egbe Serafu ati Kerubu ilu na.

Irohin ti "Eleti-Ofe" gbo ni wipe l'ojo ti nkan yi se, iya Serafu wo aso funfun pin-in bi eyiti o nlo si ibi-ipade ijo sosi egbe won, ni o ba l'okun s'orun ti o si gun ori aja lo, o si ye ategun mo ara re l'ese, o wa nmi dirodiro.

Omobinrin kansoso na ti iya Serafu yi bi ko si nile, o lo si oja, sugbon bi o ti de, ti o si ilekun ti o ri iya alaso funfun ti o nmi dirodiro l'oke, inu re dun, o sebi Angeli l'ofe fi araban on. Sugbon nigbati o ri wipe iya on ni, ni o ba l'agbe ta.

# Itan Nipa Ogedengbe Ilesha

(Lati Owo:- F. O. N. OLABISI)

Itan eleyi je itan aiye atijo nigbati baba nla Yoruba gbogbo feran arawon ti oju won sokunkun dudu. Nitorina, ko si eya Yoruba kan ti enia le bu tabi ti enia le pe on lo jare tabi ti o jebi ija ti ao soro re wonyi:

Ogedengbe je okan ninu awon Oga'gun pataki ti awon Ijesha ni laiye atijo, o si lokiki to be ge ti ko si Oga'gun ti o lagbara ju lo nigbana. Ija kan besile larin awon ara Ibadan ati awon Ijesa nigbana, idire ni pe awon Ijesa ti won wa leti Osogbo nfa ijongbon pelu awon Osogbo nipa pe ki won ma a lo si oko won ki won mu nkan ti won ba fe, ki won lo si ileto ki won ko won leru gege bi iwa gbogbo Yoruba nigbana.

Sugbon awon Oyo lo ngbe Osogbo, nitorina, eya awon Ibadan ni won, eyi ni o jeki Ibadan mura ati ba Ijesa ja. nwon wa pelu omo ogun won. Nwon koko gbogun ti Ilase ati Ibokun, odidi odun kan ni awon ara Ilase fi doju ko omo ogun Ibadan. Ibokun ni awon Ibadan ko segun, nigbati won segun Ibokun tan ni won ko gbogbo omo ogun won ti won doju ko Ilase.

Ko pe pupo lehin eyi, nwon segun Ilase Balogun Ibadan nigbana ni Ibikunle, beni akikanju enia ni. Igbati nwon ti segun Ilase tan ni Ibikunle ti ko awon omo ogun Ibadan ti nwon gba opolopo ilu ati ileto lowo awon Ijesa. Nigbehin, ogun na pari, won ko nkan ogun won wa si ile.

Lati igba ote yi, awon Ijesa ko feran awon Ibadan, won si nwa ona ati gbesan. Nwon pinnu nigbakan pe ki awon ba Igbajo ja, nitori awon ara Igbajo nse ore pelu awon Ibadan. Nitori won fe fi oro na mo awon ara Igbajo.

(Iyoku di ose tombo)

## Owo Olopa Te Onijibiti Meji

MAKURDI—Ninu Kotu ilu Makurdi ni nwọn mu awọn Onijibiti enia meji wa siwaju adajọ fun ẹsun afẹru - gb'owo.

Ọgbẹni Daniel Okorie oṣiṣẹ nile iṣẹ Reluwe ni o sọ ni waju adajọ wipe John Okafor ati Richard Orji, mu on lọ si itẹ-oku kan, nibẹ ni on ti gbọ ohun ajeji ti o paṣẹ fun on wipe ki on lọ fun Orji ni ọdunrun pọnun (£300) ki o fi da ọkẹ kan pọnun (£20,000) pada fun on.

Okorie tun sọ pe on ko ni owo ni ọjọ na, ṣugbọn ni owurọ ọjọ keji, on lọ gba ọgọta-le-nigba pọnun-ole-marun (£265) nile ifowo/pamọsi (Bank) on si ko fun Orji.

Okorie sọ pe Orji da ọjọ meje fun on lati wa gba ọkẹ kan pọnun (£20,000) na. Lẹhin ọjọ meje ti on dẹ ile Orji, ẹran ewurẹ nikan ni on ba nibẹ. Nigbana ni on lọ sọ fun awọn ọlọpa ti nwọn lọ mu awọn enia na nilu Onitsha.

Adajọ fi gbigbo ẹjọ na si ọjọ kerin oṣu May.

## Adegbenro Ni Owo-ehin gbigba ko Dara fun Adajo rara.

ABẸOKUTA— Laipẹ yi ni Alhaji D. S. Adegbenro Minista Alamojuto Eto awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Iwọ-orun Nigeria ṣe ikilọ fun gbogbo awọn adajọ Kotu-ibilẹ ti o pejọ si ibi ariya kan ti a ṣe lati ki Oloye V. A. Ilọri, Adajọ agba Kotu Ibilẹ ilu Ẹgba ti a ṣẹṣẹ sun ipo rẹ siwaju si i pe o digba o ṣe, wipe ki nwọn maṣe l'ọwọ ninu a ngba owo-ẹhin, ki nwọn si ma a ṣe idajọ wọn laiṣe ojusaju fun ẹnikẹni, nitoripe eyi ni o le mu orilẹ-ede wa niyi larin awọn ilu olokiki.

Alhaji Adegbenro ni o yẹ ki awọn Adajọ nwọnyi ma a fi arawe Oloye Ilọri nitori lati bi ọdun mejọ gbako ti o ti di Adajọ-agba ni ilu Ẹgba, nwọn ko ka nkan alebu kan mọ lọwọ ri, bẹni a ko si f'ọwọ rọ ọkanṣoṣo s'ẹhin ninu idajọ rẹ ri. On ni o bawa le awọn ọlọṣa lọ ni Abẹokuta.

Alhaji Adegbenro tun wipe ako le fi ọwọ rọ awọn ọmọ Ẹgba s'ẹhin rara nitoripe gbogbo ibiti o jẹ pataki pataki ninu iṣẹ Ijọba - Ibilẹ Iwọ - Orun ni nwọn l'ọwọ si ti nwọn si nṣe daradara. O yẹ ki eyi jẹ iṣiri fun awọn ti o mbọ lẹhin.

Irohin ko to afojuba ni eyẹ ọjọ na ti gbogbo awọn adajọ ati akọwe kotu jake-jado ilu Abẹokuta ṣe ni ile iṣere ni Imọ, l'Abẹokuta, gbogbo awọn ti o wa si ibi aṣeyẹ na l'ọkunrin l'obinrin ni nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ lọrun.

## Ejo Olugbimo Asofin Losi Kotu Ganran

ABAKALIKI— Ẹjọ ti nwọn mba Ọgbẹni Mgbada, Olugbimọ Aṣofin ipinlẹ Ila-Orun, ti iṣe ọmọ ẹgbẹ Dynamic Party ti Dokita Chike Obi nṣe Akonijẹ ẹgbẹ na nlọ si Kotu Ganran (Asizes).

Ọgbẹni Mgbada ti o ti jẹ akọwe Igbimọ ibilẹ ilu Izzi ni ipinlẹ Ila-Orun tẹlẹ ri ni nwọn fi sun ẹsun wipe o ji owo pọnun mẹtale-lẹdẹgbẹrin ati ṣile mẹdogun (£703 : 15 : 0d) owo Igbimọ ninu oṣu June ọdun ti o kọja.

Adajọ Kotu Abakaliki fi ẹjọ na si Kotu Ganran (Asizes).

# Akorin Olohun'yo



Ọgbẹni Laz Ekwueme, ọmọ ọdun mẹrin-din-lọgbọn ti o gba'yi ti o gbẹyẹ nile ẹkọ orin kikọ (Royal College of Music) nilu nla London.

Ninu ọdun tokọja yi ni Ọgbẹni Ekwueme ti ilu Oko Awka, ni ipinlẹ Ila-Orun Nigeria wa silu Oyinbo fun ẹkọ ọdun mẹrin.

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Koṣọkọ Street, Lagos. "ELETI OFẸ," LAGOS.

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV No. 811. SATURDAY MARCH 17-MARCH 23, 1962


## Eku Lakaye !!

Wosika wa ọsẹ yi ni a fi ki Oloye Adebayọ Doherty ati awọn isọngbe rẹ ku lakaye fun arojinlẹ ti nwọn ronu wọn lati ṣe idasilẹ ẹgbẹ rere kan ti a npe ni "Ẹgbẹ Alamojuto Ire Eko" (Lagos Citizens' Rights Protection Council) eyiti yio maa wa ire ati anfani ọmọ ilu Eko, gẹgẹbi a ti tẹ siwaju iwe irohin wa ọsẹ yi.

Otitọ ni ọrọ owe awọn Yoruba mọni-mọni, ti o sọ wipe "ọmọ ẹkun ni ẹkun njọ," nitoripe iwa ati iṣe eniti o ba bi ọmọ ko ni sai f'arahan lara ọmọ na. Ki Ọlọrun Olodumaare f'ọrun oni kẹ baba wa Ologbe Josaiah Doherty, baba oninurere ilu Eko nigba aiye ijọun

Gẹgẹbi ati gbọ lẹnu awọn agba wipe baba ti o bi Oloye Bayọ jẹ onigbọwọ ẹru ati ọmọ nilu Eko yi, bakanna ni iṣe ati iwa rere, ifẹ si ọmọde ati agba pẹlu iranlọwọ ti baba ti o bi Oloye Bayọ fi gba oruko "Ọga Ni Doherty" ti ko ni ẹkeji nilu Eko yi ti o fi di ọjọ oni, mbẹ ninu ẹjẹ ara Oloye wa, Adebayọ Doherty.

Nitorina, ẹnyin enia wa, ẹ jẹki a gbaruku ti awọn saraki enia ti o da ẹgbẹ na silẹ.

## Owo Olopa Te Awon Ti O Nte Owo-Pepa

Ibadan-- Lẹnu lọlọyi ni awọn ọlọpa'nu ni Ibadan mu ẹsun awọn ọkunrin meji ti orukọ wọn njẹ Gabriel Afẹ, eni ọdun mẹtalelọgbọn ati Michael Mayungbẹ, ẹni ọdun mẹtadinlọgbọn, wa siwaju Adajọ Agba Kotu kekere, wipe nwọn ntẹ owo-pepa ninu ile wọn ni Ọranyan.

Nigbati nwọn bẹrẹsi ṣe iwadi ẹjọ awọn ọdaran na, Ọga ọlọpa kekere Ẹtim Osana Odofia ni eniti o kọ s'ọrọ; o ni gerẹ ti nwọn ti ṣ'ẹnu foro fun awọn ni on pẹlu awọn enia on ba gba ile awọn ọdaran na'lọ ni Ọranyan.

Ọgbẹni Odofia ni ija ni awọn ọdaran na ko gbe awọn ni gbara ti nwọn ti f'oju kan awọn, ti nwọn bẹrẹsi f'idi fọ'gba - f'awo kiri inu ile fun bi iṣẹju mẹdogun gbako ki irewẹsi to ba wọn.

Nigbati awọn ọlọpa yi bẹrẹsi yẹ iyara wọn wo, wọn ri rọba ti nwọn fi ntẹ owo aiyederu pẹlu pọnun marun owo pepa aiyederu, ọda itẹwe pupa ati oni bulu pẹlu apo kan ti nwọn ko pọnun mẹtalenirinwo ( £403 ) owo-pepa si.

Awọn ọlọpa si mba ẹjọ awọn ọdaran na lọ.

## Onisowo U. A. C. Fun Awon Mejo Ni Anfani Eko Ọfe

xz——————:——————zx

Awọn ẹgbẹ Oniṣowo U.A.C. ti Nigeria ṣe ififunni anfani Ẹkọ ọfẹ ni ile iwe giga fun ọdun marun ni orisirisi ile ẹkọ giga ni ilẹ Nigeria lati ibẹrẹ ọdun 1962. Awọn ti o ri anfani ẹkọ yi gba ni Emmanuel Armah, Fasasi B. Kelani, Jubrila Ayinla, Raphael Mora, Felix N. Ejoh, Ebere U. Nduka, Eugene Juwah ati Veronica Ememoh.

EMANUEL, eniti nṣe ọmọ ọdun mẹtala wọ ile ẹkọ giga ti Methodist ni Eko. On jẹ ọmọ Ọgbẹni Armah, ti o jẹ osiṣẹ ẹgbẹ Oniṣowo yi ki o to ku ni ọdun 1954. Mrs. R. Armah jẹ osiṣẹ Kingsway ni Eko"

FASASI jẹ ọmọ ọdun mẹtala, o si lọ si ile ẹkọ giga ti Abẹokuta. On jẹ ọmọ Ọgbẹni A. A. Kelani ti nṣe agbowo ọja tita ni Oshogbo.

JUBRILA jẹ ọmọ ọdun mẹrinla, o si jẹ ọmọ Ologbe A. Ayinla, ti o ti gba isimi niti iṣẹ. Yio lọ si ile Ẹkọ giga Ẹgbẹ Ibo ni Kano.

RAPHAEL, eniti nṣe ọmọ ọdun mẹrinla, jẹ ọmọ Ọgbẹni E. J. E. Morah ti o nṣiṣẹ ninu ile iṣe Alakoso ohun ọgbin rara. Ile ẹkọ giga ti Enugu ni a gba a si.

FELIX, jẹ ọmọ ọdun mẹrinla, ile ẹkọ giga ti St. Patricks, Asaba ni yio ti lọ kọ ẹkọ rẹ. On jẹ ọmọ Ọgbẹni F. K. Ejoh, eniti nṣe akọwe alaṣẹ ni Keffi. Ọgbẹni Ejoh ti lo ọdun mejidilogun labẹ ẹgbẹ awọn oniṣowo yi.

EBERE, ti nṣe ọmọ ọdun mẹrinla yio lọ kọ ẹkọ rẹ ni Hope Waddell Training Institution, ni Calabar. Baba rẹ jẹ akọwe ni ibi iṣẹ awọn ọlọkọ ni Port-Harcourt, a si fun ni isimi ni ọdun 1952. Ogun ọdun ni o lo labẹ awọn oniṣowo yi.

( Wo yoku loju ewe keje )

## Ojo Isimi fun Odun Musulumi.

EKO—Ijọba Apapọ fi ikede s'ode wipe ọjọ Atini (Monday) ọjọ kerinla ati Atalata (Tuesday) ọjọ kẹdogun oṣu May, ni yio jẹ ọjọ isimi fun ọdun Ileya, Eid-el-Kabir.

Atipe ọjọ Atini (Monday) ọjọ kẹtala oṣu August ni yio jẹ ọjọ isimi fun ọjọ ibi Anabi Muhammed, Eid-el-Maulud.

Ikede yi jade lati ile iṣẹ Alabojuto eto ilu fun Ijọba Apapọ nilu Eko, ni ọjọ kọkanle-logun oṣu February 1962.




## Itan Eiye Kanakana ati Kolokolo

Lati owọ J. Ọlọrun-Toyin

Ni ọjọ kan, eiyẹ kanakana ati kọlọ-kọlọ di jọ nṣe ọrẹ pọ. Nigbati o di ọjọ kan, Kọlọkọlọ lọ si inu igbo lati lọ ṣe ọdẹ. Nigbati o de inu igbo, o bẹrẹ si wa ẹran kiri, ko pẹ pupọ ti Ọlọrun Ọba fi ọna han, nigbati o gba ibi ti Ọlọrun juwe fun u o pa ẹran nla meji. O gbe ọkan si apa ọtun, o gbe ekeji si apa osi, o nlọ si ile.

Bi o ti nlọ ni ọna, o ba ọrẹ rẹ latijọ ni odo ti o npa ẹja. Kọlọ-kọlọ ki ọrẹ rẹ yi, o ni iwọ ọrẹ mi, ẹ ku ọjọ mẹta ijọkan tun pẹlu rẹ, o ni iwọ ọrẹ mi, ... nwọ mi, mo fẹ ki a ṣe paṣi-parọ, ki o gba ẹran kan. Ki o ... mi ni ẹja nla kan. Ọrẹ rẹ ni on faramọ, ni nwọn ba parọ.

Kọlọ-kọlọ gba ile lọ, nigbati o de ile o nsu ẹran ati ẹja o yan o gbẹ daradara, bi o ti ṣe eto ẹran yi tan ni Kanakana ba wọle o ni Iwọ ọrẹ mi, on wa ba ẹ ni ... dejo ni kini o ... on.

Kọlọ-kọlọ ni kini o tun de, ti iwọ Kanakana nfi ṣọ bayi Kanakana ni o tilẹ wu on ni, Kọlọkọlọ fun ni ẹran kan, o dupẹ pupọ lọwọ rẹ.

Ki Ọlọrun gba wa lọwọ afoju fẹni nla fi ọkan fẹni', Bi iku ile ko ba pani ti o de ko le pa ni", ko pẹ pupọ ti Kọlọkọlọ jade ni ile ni Kanakan wọle de, o ba ẹran ni ori ina, o gbe ẹyọ kan ninu rẹ komọ wipe awọn ara ile nwo on, nigbati o nmu ẹran lọ.

Nigbati Kọlọ-kọlọ wọle de, o wa onjẹ jẹ, ko pẹ ti o jẹun tan ni Kanakana wọle de. Bi o ti wọle ni ara nfu, ṣugbọn o joko. Ko pẹ ti o joko ni o sọ fun Kọlọ-kọlọ wipe ẹran ti o ko si ori ina njona. Kọlọ-kọlọ dide o lọ si idi ẹran o ri wipe ẹran ko pe iye ti on fi sibẹ jade, o bi Kana-kana lere pe ṣe oko mu ẹran, oni rara, on ko de ile rẹ nigbati o jade o, ki o yara wa ẹran rẹ dada, bi awọn ara ile ti ngbọ ariwo awọn mejeji ni obinrin ti ori Kanakana ba wa, oni ọrẹ rẹ yi lo gbe ẹran rẹ. Lẹsẹkanna Kanakana ti sa jade si ita. Bi ọrẹ awọn mejeji ti ṣe pari nyi. Onikaluku ba ọna tirẹ lọ.

## AWON OLOPA MBA OYINBO TI O BA KUKU SEPO S'EJO

IKẸJA—Ogunlọgọ awọn enia ti o wa si Kotu kekere ni iwaju Adajọ Agba Ọgbẹni A. Adeshingbin laipẹ yi ni o gbọ bi ọdaran Oyinbo kan, Herbert Graham Wink, onisẹ ọkọ ofurufu (B.O.A.C.) tiṣe ba ọkunrin kuku rẹ sepọ ni alẹ ọjọ kan ninu ile ti nwọn jọ ngbe.

Ẹjọ ti Ọga Ọlọpa, Alban Ikenwa ti o ri wọn ni alẹ ọjọ na ro ni wipe bi on ti nṣe abẹwo kakiri ni alẹ ọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ ni on gbọ ariwo ẹnikan ti o nkigbe wipe "ẹ gba mi, mo fẹ ku o" Ọga Ọlọpa na ni on ya wọle na ni, 13c, Colby Avenue, Ikẹja, ti on si ri ọkunrin enia dudu kan ati Oyinbo kan ni ihoho ti nwọn si dimọ ara wọn papakoko bi t'ọkọ-t'aya.

Ọlọpa na ni on bi kuku Oyinbo na ti orukọ rẹ njẹ Moses Oayenloa lere wipe, kinni o fa a ndimọra - ẹni bayi? Moses ni Ọga on Oyinbo yi ni o ni ki on bọra ṣilẹ, on fẹ ba on ṣepọ. O ni on si sọ fun wipe obinrin ni nwọn mba ṣepọ nilu awọn ki iṣe ọkunrin. Ki on to sọ eyi tan, o ti gun ori on.

Awọn Ọlọpa ṣi mba ẹjọ na lọ lọwọ

## Alase Ile Ise Ifiweranse



Ọgbẹni Amir H. Jamal, ti o jẹ ara ilu Asia kanṣoṣo ti o wa ninu awọn Alaṣẹ Ijọba, ti a nwo ninu aworan yi, ni ẹniti aye iṣẹ tirẹ ko yipada ninu ijọba ilu Tanganyika, lẹhinti Olotu ijọba ilu na fiṣẹ silẹ. Ipo Alaṣẹ Ifiweranṣẹ ati Iṣẹ ilu kanna ti o ti wa tẹlẹ na ni o tun wa ninu ayipada titun ti nwọn ṣe.

**E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ti O Kun Fun Irohin Aladun L'osose.**

# Itan Ijapa Ati Aja

(Lati ọwọ ỌLAJIDE BABSON)

Ni Igba lailai, Iyan mu ni ilu ti Aja ati Ijapa ngbe ebi pa Aja pupọ ti o jẹ ' wipe Aja ru pipọ ti egungun ẹlhin rẹ fẹrẹ ma han ni ita. O wa di ọjọ kan, Aja gbera o lọ si oko rẹ ti o da, nigbati o de ibẹ, iṣu ko ta, agbado yọ irukẹ rẹ ko si ọmọ ninu rẹ, Aja wo titi, o ṣo mi loju, ni o ba si nlo, nigbati o dẹ oko oloko kan ni ilu keji ti o gbe fẹ iyawo, iyẹn ni oko ọna rẹ, ni o ki Oko mọlẹ, o wa iṣu, o sun diẹ jẹ, o di Iyoku wale, nigbati o de ile, o gun iyan jẹ, o sun.

Gbogbo awọn ara adugbo nsọ wipe bi iyan ti mu to yi, Aja tun ngun iyan jẹ, wọn nse wipe se tẹlẹ-tẹlẹ Aja le ṣiṣẹ, lai mọ wipe wipe nṣe ni o nlọ ji ṣu ana rẹ wa. Bẹni o nṣe nigbagbogbo, o ma nji ọ ni, ki ile to mọ a ti pada dẹ, a si ti jẹun.

O wa di ọjọ kan, Ajapa ọlọgbọn ẹwẹ ba Aja lọ, o ni ọrẹ mi, jọwọ gba mi ebi ti fẹrẹ pa n' ku to be nko mọ ohun ti mo le ṣe jẹun.

Aja ni bi o ti wi yen gan inu mi dun lati se ẹ ni ore ṣugbọn iwọ Ijapa o ko le rin, ọna ako ni jina pupọ

Ijapa ni on a nin irin eleyi dada, Aja ni ko buru, ki oji wa ni afẹmọju, nigbati o di afẹmọju Ijapa lọ kọkọ ji de ile Aja, o ni orẹ mi, mo ti de o.

Aja na ni ku abọ ọrẹ mi, se dada ni o ji? Alọ ya ni yẹn o, ṣe Aja ko ni ẹni bẹni ko ni aṣọ ibora ti ao fi sọ wipe yio tun ma mura lọ titi.

Ọ sọ fun Ijapa pe wa o, "Oko Ole Ni A Nlo Ijapa ni o ti ya, on na ṣe iṣe ole tẹlẹ ri, on papa fura si ya pe bi iyan ti mu to yi, ẹtun ngun iyan jẹ, ẹnyin ti o jẹ wipe ẹ ko feran ilẹ tutu tẹlẹ, o ṣọ nisọ ti Aja ko fi le binu.

Aja ba juwe ọna fun Ijapa, o ni ki o ba on ni oko kiki, ki Ijapa to de, Aja ti sun iṣu jẹ.

(Ko iti pari)


## OKUJA W'OLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA ỌMIRAN, EYI NI OGUN T' ONIṢOWO LE ṢE

TI OJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA AKARA GBIGBONA.

# E Polowo

**Oja Nyin Sinu Iwe Irohin**

**Eleti - Ofe**


# Ejo aso aloku ni Kotu PortHarcourt.

PORT-HARCOURT - Ọgbẹni A.O Okunna, Lọya ilu Port-Harcourt ti nwọn fi sun ẹsun ole isopanpa ati iyiwepada lori idi aṣọ aloku mejile-ladọta-le-lọdunrun. (352 Bales) pẹlu awọn enia meje miran ni Adajọ Kotu Ganran (Assizes) ti ilu Port-Harcourt da silẹ ni ọjọ Satide to kọja wipe ẹri ko to lati ju s'ẹwọn.

Awọn ti Adajọ da silẹ pẹlu Lọya na ni awọn enia mẹrin J.R. Udok, O. Chukwuma, E. Archibong ati E. Ogbonna. Adajọ sọ wipe ko si ẹri to tako awọn ọdanran na depo ti ko fi si iṣiyemeji.

Awọn enia mẹta ti Kotu ṣa s'ẹwọn ni A.A. Owoh, Oniṣowo ilu Aba si ọdun meje pẹlu iṣẹ aṣelagun, awọn meji yoku, Charles Wikinah ati Reginald Okpara ni Kotu fun ni ọdun marun ati ọdun mẹrin tẹle arawọn bakanna.

Adajọ Ọgbẹni H. M. Kaine sọ wipe atako fihan gedegbe wipe Owoh, Okpara ati Wikinah ti pamọpọ lati lo jibiti fun Ijọba.

# ALASE ETO ILU NINU IJOBA TANGANYIKA



Ọgbẹni Osca Kambona ti o ti jẹ Alaṣẹ Alaṣẹ ẹkọ iwe ninu ijọba tẹlẹ ri ni o pada di Alaṣẹ eto ilu, nigbati Olotu ijọba fiṣẹ silẹ lẹhin ọsẹ mẹfa ti ilu Tanganyika gba Ominira.

# Onisowo U. A. C. Fun Awon Mejo Ni Anfani Eko Ofe

( O bęrę loju ewe kęrin )

xz——————:——————zx

Eugene, ję ọmọ ọdun mẹjila abọ, Ile ẹkọ giga Immaculate Conception ni Enugu ni yio lọ kọ ẹkọ si i. Baba rę Ọgbẹni D.C.O. Juwah lo ọgbọn ọdun labę onișowo yi ki o to gba isimi ni osu June 1961.

Veronica, ọmọ ọdun mẹjila, ję ọmọbinrin James Enemoh, oșișẹ labę awọn ọlọkọ oju omi ni Burutu ti o ti lo ọdun mẹdọgbọn, yio lọ si ile ẹkọ giga Our Lady's High School, Effurum, Warri, gęgębi akękọ ile. Lẹhin ti o ba yege ninu ẹkọ rę, Veronica fę lati șe ișę alabojuto ni ile iwosan.

Lẹhin ti a ba fi anfani ẹkọ ọfę eyiti awọn ẹgbẹ onisowo miran ninu ișẹ owo șișe ti U.A.C. ni ilę Nigeria pẹlu, apapọ anfani ẹkọ ọfẹ ni ile ẹkọ giga ti yio bęrę ni ibęrę ọdun 1962 jẹ mọkanlelogun.

## Egbe Onisowo U.A.C. Tun Fi Enia Mejidilogun Si Ipo Alakoso

Awọn ẹgbẹ onișowo U.A.C. ni ilę Nigeria nipa itęlę aşa wọn lati fi awọn oșișẹ wọn ti o ba yege ninu Ișẹ wọn si ipo alakoso ninu ișẹ wọn șe ifilọ igbega awọn mejidilogun ninu awọn oșișẹ wọn si ipo alakoso.

Awọn ti a şẹşẹ yan nwọnyi ni a mu lati gbogbo orilẹ ede Nigeria, eleyi si mu ki apapọ enia dudu ti o wa ni ipo Oyinbo ninu ișẹ awọn onișowo U.A.C. jẹ ojilenigba (240).

# Owo Ilewe Sonu: Tisa Fese Fee

Ijẹbu-Ode-- Laipẹ yi ni awọn Ọga ọlọpa Ipinlẹ-Iwọorun da awọn ọtẹlẹmuyẹn, ọlọpa'nu wọn jade wipe ki nwọn maa wa ọkunrin Ọga olukọni ile ẹkọ giga kan ti orukọ rẹ njẹ D. A. Kẹmiki, ẹni adọta ọdun, kiri boya o le la awọn loye nipa owo Ile-iwe tabua kan ti awọn ọmọ ile ẹkọ ti a npe ni Odogbolu Local Government Modern School, san ti o si di awati.

Onirohin wa ni ara ilu kan ti nwọn npe ni Imodi ti ko ju ibusọ mẹta lọ si Ijẹbu-Ode ni Ọgbẹni Kẹmiki ti a nwa na, o si nfi igi rin nitori ẹsẹ kan ti o ndun. Tẹlẹ-tẹlẹ, Ọga ilewe kan ti a npe ni Anglican School, l'Aiyepe l'ọba Ijẹbu-Ode, ni o ti nșe Ișẹ ki o to lọ si ilu Oyinbo nwọn ọdun marun lati kọ ẹkọ ișẹ tișa si, Ẹgbẹrindinlogun pọun (£3,200) ni owo ile-iwe (school fees) na ti nwọn nwa.

## Oba Awujale Fe Lo Si Meka

IJEBU—ODE—Laipe yi ni Ọba Alaiyeluwa Sikiru Kayọde Adetọna, Ọgbagba Keji, Ọba Awujalẹ nilu Ijẹbu sọ fun awọn Musulumi Ijẹbu-Ode ti o wa ba șe ajọyọ ọdun itunu awẹ wipe on ti mura tan lati lọ si Mẹka ninu ọdun yi, on yio si gun Oke Arafa pẹlu awọn ogunlọgọ awọn enia ti o mbọ wa lati gbogbo agbaiye kakiri.

Ọba yi ni yio si jẹ ẹnikini ninu awọn Ọba Awujalẹ ti yio kọ lo si Mẹka nitoripe Ọba Awujalẹ kan ko lọ si ẹhin-odi kan ti o kọja ilẹ Yoruba ri.

Ọba yi ni bi on ba kuro ni ilu Mẹka ati Medina tan, on yio fi ẹsẹ kan de awọn ilu miran bi ilu Oyinbo ati agbegbe rẹ.

Fun irinajo yi a ti fun Ọba yi ni aye oșu mẹta gbako.

# Olotu Ijoba Ilu Tanganyika Titun



Ọgbẹni Rashidi Kawawa, ọmọ ọdun mẹta-le-lọgbọn ti o ti wa ninu awọn ti o mu opo ijọba dani, ti ko ni ile ișẹ, tẹlẹ ri, ni o di Olotu Ijọba ilu Tanganyika nigbati Ọgbẹni Julius Nyerere, fișẹ silẹ ti o wipe on yio dojukọ atunșe eto ẹgbẹ ti on jẹ Alakoso rẹ.

Ọgbẹni Kawawa, ti o jẹ Musulumi enia, ti șe Alakoso ẹgbẹ Apapọ awọn oșișẹ ilu Tanganyika ki nwọn to yan si ipo Alașẹ Ijọba Ibilẹ.

ELETI-OFE D'ARABA

## Nwon Fi Dokita Chike Obi Sun Esun Owo gbigba Lati Ile Okere

xz———:———zx

Laipẹ yi ni Dokita Chike Obi, Olori ẹgbẹ oṣelu kan ti a npe ni "Dynamic Party" dagbere fun awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ wipe on fẹ ba ọkọ ofurufu lọ s i l u Aganyin ti nwọn npe ni Ghana nisisiyi ati pe on nlọ gba iranwọ owo lati lo fun ẹgbẹ on l'ọhun ni.



Ko pẹ lẹhinti o pada bọ sile ni ọkan n i n u awọn ẹgbẹ rẹ ti o ti fi ẹgbẹ na silẹ, ti o si ti ṣe akọwe ẹgbẹ na ri, ti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni S.O. Abiara ṣe ẹnu foro fun awọn oniwe i r o h i n pe on le f'ọwọ sọ ẹiya ni gbangba pe iranwọ owo ti Dokita Obi nri gba lọwọ awọn ilu ti o f'aramọ Rọṣia ati bẹẹbẹ ni o jẹ ki Dokita Obi fẹ sọ ijọba Nigeria di ijọba "A ko-ga-jura lọ" (Communist).

Ọgbẹni Abiara sọ wipe ni idunta sẹhin, ki on to da ti on silẹ, owo ti ẹgbẹ Dynamic Party ri gba lọwọ awọn alatilẹhin ẹgbẹ na jẹ ọgbọn ọ k ẹ pọnun (£600,000) ninu eyi na ni nwọn pin fun awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti nwọn njẹ "Nigerian Youth Congress" pẹlu "Nigerian Trade Union Congress".

Ọgbẹni Abiara ni ẹgbẹdọgbọn, pọnun (£5,000) ṣarai ni [illegible] ko fun awọn ẹgbẹ Onirungbọn, "Nigerian Youth Congress" ati pe ẹgbarun (£10,000) ni o bọdi [illegible] awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ "Trade U n i o n Congress" eyiti Ọgbẹni Imoudi nṣe Olori w ọ n. Ajumọṣe yi l'ejẹ ki Dokita Obi ati Ọgbẹni Imoudi ọ rin irin-ajo lọ si ipinlẹ Ila-orun nigbati ọjọ idibo ibẹ ku si dẹdẹ.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 22376; Olotu L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.

## Agogoro Eyo, Huu-Haha!!

Loni Satide ni ilu Eko yio kun fun awọn ajeji enia ti o ti idalẹ wa woran ere Ẹyọ Adamu-Oriṣa ti a nwo aworan rẹ ninu iwe yi.



### ARO EYO

Abẹyọ, Abẹyọ,
Abẹyọ jẹ
Kelẹkelẹ ma so'lore,
Ol'ore mẹ'wo,
A bere ẹhin?
Ẹhin wa l'ọwọ asuke e,
Asuke ti tani? T'orisa,
Orisa nkọ? T'ọmọ araiye,
Ọmọ araiye nkọ? T'Ọlọrun,
O ma ṣe mẹrẹn-mẹrẹn,
O ṣe ti'mọ ti'mọ.
Ile wa l'awo gbe ti wa,
Gẹlẹdẹ t'ejilu ji mala,
Ile wa l'awo gbe ti wa,
Gẹlẹdẹ t'ejilu ji mala,
O fi Akala m'awo ẹsi Ikọle,
On lo lọ mu'ko Ẹlẹyọ
Mo yọ fun ẹ, ka yọ fun 'ra mi,
Oju ko ma se 'gi orere,
Afọnja Alagemọ ki nse abuta,

HU U U HA HA !!

**Eleti-Ofe Gbarada, T'elegan L'oku**